**Ọrẹ agba**

ỌPẸLẸKẸTẸ ndagba, it u adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọ a o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.



# Irohin Yoruba

NO. 118 WEDNESDAY JULY 29 — TUESDAY AUGUST 3 1964 KOBO MẸTA 3D



AI

POLOW

ninu iw

Yoruba' Ol

ti o nta t

bi akara gbi


# IJOBA AKINTOLA FE YAGBE SORI AGA

## —'Gbenro



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Alhaji D. S. Adegbenro, adele babasale egbe Afenifere ti tu asiri pe Ijoba egbe NNDP ti pinnu lati fi kun iye awon olopa Ibile ti o wa ni Ipinle Iwo-Orun, ti nwon yio si to iriowo gegebi ona lati ko awon janduku egbe na wo inu olopa ibile. O tun fi esun kan pe gbogbo awon Igbimo Afunso Ijoba Ibile ni egbe na ti fen ni ase lati fi owo awon asanwo-ori ra oko lorisirisi fun lilo awon olopa Ibile na bi o tile je wipe awon Igbimo na ti tawona nisisiyi, ti nwon ko si ri owo lati se ise itura fun awon enia agbegbe won.

Fakanna ni o tun tu asiri pe gbogbo iwe ti awon Igbimo Ijoba Ibile na ti ko si awon ile ifowopamo ti o wa ni Ipinle Iwo-Orun lati ya owo ni awon ile ifowopamo na ti ko nitoripe awon Igbimo na ko iti da owo ti nwon ya teletele pad .

Alhaji Adegbenro tu gbogbo asiri wonyi ninu ipade pataki kan ti o ba awon oniwe irohin se ni ile Oloye Awolowo ni Oke-Ado, Ibadan ni ojo kerinlelogun osu yi.

Alhaji Adegbenro so wipe ero Oloye Akintola ni lati ko Iwo-Orun sinu gbese nlanla fun Ijoba miran lati san ki o to fi ipo Olotu sile. O kilo fun awon onisowo moto lati sora gidigidi nipa tita moto awin fun awon Igbimo Afunso Ijoba Ibile, a fi bi nwon ba fun won ni idaniloju wipe awon yio san owo fun ara won nitoripe Ijoba egbe Afenifere ko ni torunbo gbese Ijoba egbe NNDP.

O tun tu asiri wipe egbe olopa Ib le nje awon egbe Afenifere ati Alakuko ni iya bi nwon ba ko lati darapo mo egbe NNDP. O wa so pe nigbakugba ti olopa yowu ba koja aye re, ona yio wa si sile fun awon enia lati lo ohunkohun lati gba ara won la



ALHAJI D. S. ADEGBENRO

Lori awon osise Igbimo Ijoba Ibile, Alhaji Adegbenro tu asiri wipe Ijoba NNDP ti se ayidayida ofin lati ma fi je osise ti ko ba gba ti won niya.

Lori awon oba, adele babasale egbe Afenifere tun se ikilo wipe ki awon oba fo gedegede ninu iselu nitori anfani ara won. O wa se alaye wipe iyato mbe ninu fifara mo Ijoba ati dida akowe itankale egbe oselu ti nse akoso Ijoba.

Alhaji Adegbenro wa pe akiyesi si iya ti awon Igbimo Ijoba Ibile fi nje awon omo egbe Afenifere ati Alakuko nipa bibu owo-ori gbakọ fun won ati nipa fifi iya je won ninu awon ile ejo ibile. O so wipe nipase iwonyi ogunlogo awon omo egbe meji na ni o wa ni ogba ewon bayi.

Ni ipari, Alhaji Adegbenro wa ro awon enia Ipinle Iwo Orun lati fara da isoro ti egbe Domonu nghe ko won loju lojojumo "titi ti ojo idajo yio fi de."

# 'Maja *gb*'owo lati jẹri mọ Awo'

ONIṢẸGUN Oyinbo kan ni *Eko*, ọmọ Dokita Akinola Maja baba ẹgbẹ Afẹnifẹre tẹlẹ, *Dokita* Ọladipọ *Maja* "gba owo" lati jẹri ninu ẹjọ iditẹ si Ijọba ti nwọn fi kan Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn ogun enia mir*an*.

Eleyi ni ọrọ ti o jẹ *j*ade nile ẹjọ kan ni Ikẹja ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu keje ọdun yi lati ẹnu Ọgbẹni Sidi Khayam, asiwaju kan ninu ẹgbẹ oṣiṣẹ ti nwọn mba ṣe ẹjọ pẹlu *D*okita Victor Allen, Oluṣegun Adebayo ati Jonas Abam lori ẹjọ iditẹ.

Ọgbẹni Khayam sọ ọrọ yi ni*bi* iwadi kan ti nwọn nse lori gbigba ẹjọ ti awọn ọlọpa sọ pe o kọ silẹ ni osu *k*ẹfa ọdun yi gẹgẹbi ohun ijẹri. O bọ sinu apoti ijẹri l hin ti adajọ Ọgbẹni F. B. Wicklife ti sọ wipe ki o wa fi ẹnu ara rẹ sọ ohun ti oju rẹ ri nipa ohun ti awọn ọlọpa *we* mọ lẹsẹ.

Ọgbẹni Khay m binu

(Wo oju ewe kẹjọ)

# Ẹlẹdẹ pa Ọmọ ag*b*ẹ jẹ

Pabambari ni irohin kan ti o jade ni ilu Kalaba laipẹ yi nigbati agbo ẹlẹdẹ ti ebi ti npa foroforo kan bu ọmọ ẹgbẹ Agbẹ agbegbe na kan, Ọgbẹni Okon Harry Akpan jẹ titi ti o fi ku.

Irohin kan ti o tẹ wa lọwọ lati ago ọlọpa ni Kalaba sọ pe nṣe ni Ọgbẹni Akpan nkanju lọ si ibi ipade kan nigbati o subu sarin awon agbo ẹlẹdẹ na ti nwon si bẹrẹ si ni yajẹ bi ẹni ya ẹja jẹ.

Agbo ẹlẹdẹ na bu jẹ pupo ni gbogbo ara, ti ko le fi de ile iwosan titi o fi ku finrinfinrin.

# Ijọba gba onjẹ lẹnu ọba

IBI ile iṣẹ akoso Ijọba Ibilẹ Iwọ-Orun ti pasẹ pe ki Igbimọ Afunsọ Ijọba Ibilẹ agbegbe Ijẹbu-Rẹmọ da Ojilelẹdẹgbẹfa o le pọnun meji (£1,142) ti oba Akarigbo ti Ijẹbu-Rẹmo, Ọba Moses Awolesi ngba lodun duro.

Ile ise Ijoba na tun fi kun pe ki Igbimo Afunso na da inawo ti o jẹ mo itoju afin oba na duro titi ile iṣẹ Ijoba Iwo-Orun yio fi se aseyori ipinnu won.

Awon Igbimo Afunso Ijoba Ibilẹ Ijebu-Rẹmo ṣe ikede yi ninu ipade idagiri kan ninu eyiti nwon ti ka iwe asẹ na ti o jade lati Ibadan lẹhin ti Igbimo oluwadi ti Ijoba Iwo *O*run yan lati pari ija larin oba na ati Igbimo Ibilẹ NNDP rẹ ti jiyin iṣe won.







